The Chief Sec to the Government Lagos


### AKANSE

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 69. SATURDAY, NOV. 3, 1923. Sixpence.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

"'Specialities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Baliam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads etc., etc., etc."

Ọgbẹni DURO THOMAS

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to şẹşẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Māse leti ita Faji, l'Eko.

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

**J. F. SICK** ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode bilā, Peti *Glover Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO.





Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ Masini-Aranso ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu Masini na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranşẹ *Cement* ati panu!kikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ Asiri nipa Owo. Irohin ko to afojuba.

OGBENI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Oja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Oja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awon ohun xikole fun tita ni owo opoku-oyoku.

O ti nsowo Irin Işe lorişirişi lati adota odun sehin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni OGBENI na je ninu awon onişowo Irin Işe ni ilu Nigeria.

OKO tita wa ni owo po o.

---

**B. O. Joseph**
*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

Cotton.
Sundries.
Hardware.
Provisions.

27, Koseh Street, Lagos.

---

**The British Psychological Institute**
OF BOLTON, ENGLAND.

teaches by Correspondence the following Sciences :—Psychology, Philosophy, Phrenology, etc., etc.

For complete particulars, apply to the Official Representative of the Institute for Nigeria and Gold Coast Colonies

C. GLADSTONE-MACAULAY,
P.O. Box 384,
Lagos.

*Youngmen, for future's sake, be on the alert.*

---

**THE LAGOS HOTEL.**

Iced Drinks of every description on sale at the above popular Hotel.

Clients' comfort occupies a prominent part in the programme of the establishment.

Billiards playing forming a centre of attraction.

TERMS :—Strictly Cash.

H. H. KING
*Proprietor.*

Portonovo Market St.,
Lagos.

---

ILE ERO TI EKO.

Ohun mimu Olomi didi to np'ongbe e nbe nihin lorişirişi fun tita.

Ko si ona ti a ko ngba fi te a onibara wa lorun.

*Billiards* idaraya si wa fun enikeni la sere. Owo-lowo la fe.

H. H. KING
*Oni-nkan.*

Ita Oja Ajaşe, Eko.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

ESU LO NṢE CHARLIE!

Ni *Friday* ọsẹ ti o kọja bi ọmọ kan ti fẹ ra ōtẹ (*Postage Stamp*) ni Ile-ifi-iweranṣẹ (*General Post Office*) nibi bẹni 'Isẹkiri kan ti o njẹ Charlie tọwọ bọ apo ọmọ na o si ko owó *Currency* pupa mẹta ti o jẹ pọnun mẹta lọgan bẹ lo ṣi pī, ọmọ yi bẹrẹ si ke ki o to wa ri oni Mọto kan o si sọ ole ti a ja a fun u tobẹ ti iyẹn si gbọn Mọto rẹ to si ba ọmọ na; wàràwẽré bẹni Ọgbẹni R. B. Reis ẹbọra Ṣabu Ọlọpa a-bi-mimu-ole-lọtọ yara ki ogbole yi mọ'lẹ bi ole na si ti fi ọwọ sẹnu, bẹni nwọn gbọn lọwọ, kilo'ṣe bi igara na ṣe? Nṣe li o si jẹ £3 *Currency* ṣamuṣamu; o dabi ẹniti o sọ pe kaka k'eku ma jẹ sèsé, a fi ṣ'awadanu o si run gbogbo rẹ womu-womu; bi o si ti ni ki on gun olori Ọlọpa na ni ọbẹ ti o mu dani bẹni ẹlẹgiri na yẹ o si tun ole na lọrun-ọwọ ṣinṣin titi ọbẹ na fi bọ silẹ ni *Monday* ọsẹ yi ni a ṣẹṣẹ da Ṣẹria fun u. Adajọ kekere si fi s'ẹwọn oṣupa mẹsan pẹlu iṣẹ aṣẹgan.

ẸGBẸ TUNLUṢE GBỌRẸGẸJIGẸ.

Ara-mbada ni Ipade nla ti awọn Ẹgbẹ *Democratic* ṣe ni Ile Afari Ogun ni *Saturday* ti o kọja eyiti ọgọrọ awọn Ọmọ-Ẹgbẹ pesẹ si, Alaga Ọlọla Onimọran J. Egerton Shyngle sọrọ o si ba awọn ẹka Ẹgbẹ na ti Ẹnu Ọwa ti nwọn ṣe laifi ninu ere idaraya ti nwọn ṣe ni Ilupesi ni ọsẹ meji sẹhin wi nipasẹ ti orin ēbu ti a gbọ pe nwọn kọ, Alaga sọrọ nipa ti iku Lemọmu Braimọ tohun-tẹnu bẹni Ọgbẹni Herbert Macaulay de o si gbe Alaga lẹsẹ pe ẹnikẹni ti Ẹgbẹ ba ri ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ ti nkọrin ēbu bu ẹnikẹni pe Ẹgbẹ yio fa irufẹ ẹnibẹ fun awọn Ọlọpa ki ofin si jẹ oluwarẹ niya bi o ti tọ, ati pe a o si yọ irufẹ ẹni bẹ l'ẹgbẹ; oni ọrọ ebu kọ ni o de'lẹ nisisiyi bikoṣepe ki a papọ fun rere Ilu wa. Ọgbẹni Macaulay tu ọfọ Ọgbẹni J. W. Vaughan ti o ku lọna Ilu Oyinbo nigbati o mbọ wa'le on ati aburo rẹ Ọgbẹni B. C. Vaughan ati bi a ti sin oku rẹ ni *Gambia*. O sọ ti kiki ti on ati Ọgbẹni Shyngle lọ ki Ọgbẹni Alli Balogun ati awọn ẹbi Lemọmu Braimọ ologbe o si sọ bi Ọgbẹni Alli Balogun ti gba wọn tọwọtẹsẹ ti kiki na si jẹ iyanu fun u; o ni ki gbogbo Ajọ dide duro fun iṣẹju kan fun ami ọwọ ati idagbere fun ologbe J. W. Vaughan ẹniti o jẹ ọmọ Ẹgbẹ na ni igba aiye rẹ ẹniti ko si kẹrẹ si iṣẹ rẹ gbogbo fun ilọsiwaju ilu ati iran rẹ; gbogbo ajọ si dide wī tobẹ ti a le fi gbọ iro abẹrẹ ti o ba bọ silẹ.

Ọgbẹni Macaulay sọ ti waya ti o ri gba lọwọ awọn ọmọ iya wa ti nwọn nbọ wa si Ajọ Igbimọ Aṣofin Ijọba eyiti a ṣe lọsẹ yi, ninu waya na nwọn sọ pe awọn yio gunlẹ ni ọjọ *Sunday* ti o kọja.

Sẹkitẹri J. Bagan: Benjamin ka iwe iṣẹ ti ẹgbẹ ti ṣe sẹhin Ọgbẹni James Alẹṣinlọyẹ si ṣe ogbufọ Ipade na. Bẹ si ni Ọgbẹni A. Bank Anthony jihin owo ti o ri gba ninu owo Ẹgbẹ (£95 11 0) ti a da si lọwọ ti o si ti fi si *Bank* o si fi iwe-ẹri-owo na to rigba ni *Bank* han Alaga ati awọn isọri ninu Ẹgbẹ na.

Ọgbẹni Macaulay sọ ti wiwọ Ẹgbẹ ti Ọgbẹni Spencer Savage (ẹniti o de ni ọjọ *Saturday* na gān lati Ilu Oyinbo) wọ Ẹgbẹ, ti o si jẹ didun inu rẹ lati ba wa pade.

Ọgbẹni Macaulay kede iwọ-ẹgbẹ ti Ọgbẹni Adebẹṣin Fọlarin *Lawyer* ati *Editor* Iwe Irohin ofin ti oṣoṣu ti a npe

ni *Nigerian Law Journal* Ipade tuka niwọn agogo meje alẹ.

NIGBANA NI A O FI AYỌ RU ITI WA 'LE.

Alufa M. S. Cole lọ ṣe Isin Ikore ni *Church* C.M.S. ti Ọta ni ọsẹ yi, o si pada bọ wa'le ni ọjọ *Tuesday* tokọja. Ẹ ku ọba isin.

AWỌN ỌMỌ JAGUDA GB' ODE.

Ni *Saturday* tokọja, a gbọ pe ọgbẹni R. E. Carrena ti Ita Bamgboṣe fi £7 ni *Currency* ran ọmọ rẹ kan niṣẹ, awọn ọmọ Jaguda si tọwọ b' apo gbe owo na bam-bam !!!

ORI KO MỌ 'BUSUN KO TUN 'LẸ 'BẸ ṢE.

Tẹdun-tẹdun la fi jihin iku ọgbẹni wa J. W. Vaughan ti Ita Kakawa, ninu ọkọ ni agbakun, nigbati t' on ti aburo rẹ ọgbẹni B. C. Vaughan fi ndari bọ wa si 'le lati Ilu Oyinbo nibiti nwọn ti lọ niwọn oṣu diẹ sẹhin. A si sin i si Ilu Gambia.

Oninure sān ni ọgbẹni na jẹ bi o tilẹ jẹ pe Olowo-soke-dilẹ ni sibẹ ko jẹ fi oju pa ẹnikẹni to ba ba nkan lọ sọdọ rẹ rẹ lai. O ni ẹbun orin Alarandun o si ni iṣe oriṣi orin ti o ṣe ti o si tẹ to pin lọfẹ fun gbogbo enia ; Oloye *Deacon* ni *Church* rẹ *( Ebenezer )* ni iṣe, o si mọ iwe Bibeli jinlẹ. Ki Baba gbe e s'afẹfẹ 're. A si ba aburo, aya, ọmọ, ẹbi, ati iyekan rẹ daro ọfọ nla yi.

K' ỌTUN WẸ OSI, K' OSI WẸ ỌTUN, OHUN ALARINRIN LOJẸ.

O ta si ni leti fẹnrẹn pe awọn Ẹgbẹ Parakoyi eyini ni awọn Ẹgbẹ oniṣowo ti Eko ṣe ipade aṣiri pẹlu diẹ ninu awọn Aṣaju Ẹgbẹ Tunluṣe lọṣẹ yi lati jiroro ilọsiwaju nkan. Iyẹn wun wa o !

ALAFIA K' Ẹ WA BI ?

Pastor A. Adedeji Ishola npete ati ṣe Isin Alafia ni *Church Brotherhood* lọla ninu Isin Alẹ, ki ile kun ki ọna bo lo tọ lati gbọ Oyinmọmọ ati ọrọ Ẹkọ Ojiṣẹ-Ọlọrun a wasu-ma wa ti 'ṣẹ yi.

ALUFA SA LEYI, L' AIYE ỌBA !!!

O jẹ ohun ẹdun wa lati gbọ pe ọkan ninu awọn Alufa Ijọ Onigbagbọ kan nibi kọ jalẹ lati sin oku talaka *Member* rẹ kan ni lọlọyi, nigbati awọn kan tọ ọ lọ nitori akuṣẹ Ologbe na. A gbọ pe Alufa na nwa awawi pe ologbe na ko san owo *Class* ati pe ki nwọn lọ ba on wa "Mọfọ" ti on yio wọ lọ si Itẹ ati oriṣiriṣi masọ ọrọ ba-wọn-ni. Eyi ha dara? Enyin sunmọ ni ka mọ 'ṣe ẹni, enia gb' okan niyi !

---

ÈRO "*AKABO,*" KĀBỌ!

Ẹ KU EWU ỌKỌ.

---

Bi Ọkọ Elefi, "*Akabo*" ti nbọ li ori omi li Egun Ọya ni Sunday ti o kọja, bẹ li o gun si Ibode ni iwọn agogo marun ọjọ alẹ. Kabọ kabọ !! Kabọ !!! ti awọn enia nki awọn ero ti de lati inu rẹ, fihan wipe dajudaju, Bishop Howells ati Mrs. rẹ ti a ti nreti de pẹlu awọn Bọkinni Ọlọla ti a ti yan si Ajọ Igbimọ Aṣ'ofin li *Nigeria*, eyiti a ṣe ni ọjọ meji gbako li ọsẹ yi.

Orukọ awọn Bọkinni Ọlọla na ni iwọnyi:—

Ọmọ Ọba K. Ata Amọnu,—*Lawyer* Ọpẹlẹngẹ.

Ọgbẹni Isaac Mba,—A-mu-bi-ina.

Ọgbẹni Pepple,—Apọn-b'epo-rẹ.

Ọgbẹni Obunawu,—A-kuru-yẹ'jo.

Ni Monday ọsẹ yi ni a ṣe alabapade wọn ni ile Ọgbẹni Ogidan Ololа-iju, Herbert Macaulay: jagun papa ko si ni ile : ṣugbọn gẹgẹ bi a ti ṣe ori 're, bẹni a ri ọrẹ wa kan, Ọgbẹni S. W. Duncan Abẹrin fa-ni-mọra, ẹniti o fi wa han ikọkan ninu awọn Gbajumọ wọnyi ; lọgan, Ọmọ Ọba K. Ata Amọnu ti mọ wa nipa riranti igbati tawa-tirẹ ṣe pade ni *Conference* ekini ti enia dudu ti a kọkọ ṣe ni Accra ni ọdun 1920 ninu eyiti awọn Ile Eko yan awa, Alufa Patriarch J. G. Campbell, Ọgbẹni Adeniji Olugbile lọ si Ipade na lati ṣe oju wọn.

Ọgbẹni Duncan fi Ọlọla Obunawu han wa ; lọgan, Bọkinni na si ranti igbati a wa si ilu rẹ, Onitsha, ni ọdun 1917, ti o si fi gba wa tọwọ-tẹsẹ.

A fi awọn Ọlọla ti o ku han ni, awọn bi Oloye Isaac Mba, Oloye Pepple, nwọn si ki wa pẹlu ọyaya ati inu didun ; a si fi iwe kekere oloruko wa *( Visiting Cards )* fun ọkọkan awọn Ọlọla na.

1. Ọmọ Ọba K. Ata Amọnu ni awọn Calabar yan lati ṣe oju wọn.

2. Oloye Isaac Mba ni Gomina yan lati ṣe oju apakan ilu Ibo.

3. Ọgbẹni Pepple ni Gomina yan lati ṣe oju awọn ara Opobo ati agbegbe rẹ.

4. Ọgbẹni Obunawu ni Gomina yan lati ṣe oju awọn ara Onitsha ati agbegbe rẹ.

[*Editor*,—" EKO AKETE."]

# Open Letters.

To CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

## No. 36.

To

The Honourables,

J. EGERTON SHYNGLE, ERIC. O. MOORE,

C. C. ADENIYI JONES, SAMUEL HERBERT PEARCE.

*Members of The Legislative Council, Nigeria.*

Honourable Members of The Legislative Council,

Please allow me to congratulate you on having crossed the Rubicon by taking your Seats this week in that "Parliament of Nigeria" as Members for Lagos, and Abeokuta.

Always call to mind, the significance of those lines by Pope,

"Honour and Shame from no condition rise,
Act well your part, there all the honour lies."

Then the cheap gibe, and disappointed yells of your political opponents will be to you as water thrown on the back of a drake—ineffectual outbursts.

EKO AKETE.

## No. 37.

To

HERBERT SAMUEL HEELAS MACAULAY, ESQ., C.E.

Kirsten Hall,

8, Balbina Street, Lagos.

My Lord Derby,

A bird has just whispered in my ears that this month exactly fits in with your Fifty-ninth Birth-Day: consequently, I hasten to send my congratulations with every wish for many happy Returns of the auspicious day.

To say that the praise of your multifarious duties in the unstinted Service you give to your race and country, and no less than to your King is in everybody's lips, is to give expression to poverty of language: to posterity alone is committed the just recognition of the proper appraisement of your works for struggling humanity, which such appraisement will serve as a Monument more lasting than brass.

In you, Sir, I find to be true *verbatim, et literatim*, and may I say *et puntuatim?* This undying couplet.

"One crowded hour of a *Useful Life*
*Is worth an Age without a Name*
(With apologies to Scott)

Again I repeat, many happy Returns of this auspicious day.

EKO AKETE.

## No. 38.

To

The Honourables

Prince K. ATA-AMONU, Chief ISAAC MBA,

Messrs. PEPPLE and OBIAWU:

*Members of The Legislative Council, Nigeria.*

Gentlemen,

I extend to you individually, as well as collectively, my right hand of fellowship in welcoming you to our shores.

You will no doubt agree with me, when I say that this is the first time to the best of my knowledge and belief in the history of this growing Dependency, or of British West Africa for the matter of that, in which a tangible concession is given to the *intelligentsia* of a British possession to have a direct voice in the management of its affairs by the statesmanlike system of the FRANCHISE: in this new era you are called to play your part worthily, and to the best interest of the respective countries which you have the honour to represent in that Honourable Board.

Having regard to the confidence reposed in you, it is hoped, you gentlemen, whether elected or nominated, will see to it that nothing but SERVICE in its highest connotation shall be your Watch-word to your King, your Country, and your Race: it gladdens the heart to see how whole-heartedly you were received by the community through its accredited representative body—The Nigerian National Democratic Party: and during your short stay with us, it is my burning desire that we should know more of one another as our kith and kin, for after all, there is much in the saying, "Blood is thicker than water."

Good Luck !!!

EKO AKETE.

# IHOHIN AJỌ IGBIMỌ AṢE'LU KINI TI NIGERIA.

[*Nipa Atari Ajanaku.*]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

O le diẹ ni ọdun mejile-lọgbọn loni ti Ijọba Gẹsi ta asia alafia si ilu wa: ti a ko si ri ogun, ọtẹ, idagiri ati irukerudo mọ; ti opin si de si owo-ẹrú, owo buruku ti o nṣọ ilu nla di ahoro, aya di opó, abiamọ di alailọmọ, ọmọ di alaini-baba—ani owo ti o sọ ogunlọgọ awọn baba nla ati iya nla wa di ẹdun-arinlẹ, ati ẹniti a nlo ni ilo ōmi ojo ni orişirişi ilu ajeji, li aika ọpọlọpọ ninu wọn ti a fi ṣe paşiparọ ewe taba, ọti ati nkan miran ti ko nilari.

Oyinbo de, aiye d'ẹrọ. Ọlọrun ba wa ṣe e, O si ba Oyinbo na ṣe e pẹlu lati ma jẹ ifa wa li akoko. Jẹ-ki-nịẹ li o nmu ayọ dun; ṣugbọn ni igba miran, o dabi ẹni wipe Oyinbo nkan li o nje işàki ati ọrá, nwọn a wa fi egungun ati ẹdọfóro

silẹ fun wa. Enia dudu iba le fi ẹsẹ kọ iwe, ki Lọya rẹ muna bi ti Ṣingulu (Shyngle,) ẹni rirán ni iṣẹ li o jẹ fun Oyinbo. Irufẹ iyatọ bayi ko yẹ ki o wa li arin awa pẹlu Oyinbo; nitori idi eyi ati nkan miran bẹ, ni a fi nkigbe wipe o to akoko fun wa lati ni Aṣ'oju ninu Igbimọ Aṣe'lu. Ọlọrun si gba adura wa ni ọjọ ogun oṣu Sẹptẹmba ti o kọja nigbati ilu yan Lọya Shyngle, Moore ati Dokita Jones. Ki Ọlọrun ki o pẹlu wọn, ki O ma si gbagbe awa na; papa "Ejo-ngboro," baba Ogedengbe, ẹniti wahala ati ãyan rẹ fun ire ilu ko fi ara sin.

Awọn mẹta ti a yan yi wúyè, nwọn si bura ni "*Legislative Council Chamber*" ni ọjọ Alaruba, (Ọktoba 31.) Ile kun, ọna bo, ojo ibukun si rọ ni ọjọ na. Ọpọlọpọ ọkunrin, obirin, ọmọde ati agba li o si ba wọn ṣe ẹyẹ. Nigbati agogo mẹta ọsan ku ogun iṣẹju, awọn Ṣọja (*Nigerian Regiment*) fun fere "Ki Ọlọrun gba Ọba la," gbogbo enia ti o wa nibẹ, oyinbo ati enia dudu si ṣi akẹtẹ wọn lati bu ọla fun Ọba ti o wa ni Ilu Oyinbo—ẹniti Gomina Clifford jẹ Aṣ'oju rẹ nibi. Oyinbo mọ iyi Ọba pupọ; ṣugbọn o rọ awọn enia lasan miran ninu wa lọrun lati pọn idi Oyinbo Korã (*Syrians*) lá, ju ki nwọn bu ọla fun Ọba wa.

Kabiyesi! Ẹni fi oju di Ọba, àwówo a wo o.

Nigbati agogo mẹta ku iṣẹju mẹdogun, Gomina wọ ile pẹlu Igba-keji rẹ, Sir Donald Cameron, ọrẹ enia dudu. Lẹhinna, a bura fun gbogbo awọn ti ilu ati Ijọba yan si Igbimọ; lẹhin ibura, Gomina ka waya (*Telegram*) ti Ọga rẹ, (Secretary of State for the Colonies) fi ba Eko yọ fun iru Igbimọ yi, o si tun ka esi ti on papa fi ranṣẹ pẹlu. Lẹhinna Gomina sọ ọrọ iṣiri pupọ ti o ti tẹ si inu iwe, ṣugbọn ti ẹnikẹni ko ri ṣiwaju ọjọ Igbimọ. Lẹhin na, nwọn fi esi si gbogbo ibere ti o wa nilẹ, ati ibere ti Oyinbo Osborne, Lọya Shyngle, Lọya Moore ati Dokita Jones. Diẹ ninu esi wọnyi tẹnilọrun, iyoku yio ni a-ri-yan-ji-yan ninu ki a to pari rẹ.

Lẹhinna, Ọgbẹni Kitoyi Ajasa sọrọ, ọrọ rẹ si dara; o si dupẹ li ọwọ Gomina fun iru anfani Igbimọ ti o fun wa yi. Ọpọlọpọ enia ni ko mọ ibiti a npe ni "*Colony Division,*" ilu ti Lọya Ajasa nṣe oju rẹ; ẹlomiran wipe Oworonṣoki ni, ẹlomiran ni Ajiran, Leke, ati Badagry. Nitorina, a bere wipe, Ewo-lewo?

Lẹhin ti Lọya Ajasa joko, Lọya Shyngle sọ ọrọ ni iba ṣoki, o si jẹjẹ wipe awọn yio sa ipa wọn lati ran Ijọba lọwọ ninu ohunkohun ti nwọn ba dawọle lati ṣe fun ire ilu. Gomina ati gbogbo ẹniti o wa nibẹ si patẹwọ.

Lẹhin eyi, Gomina ṣe ẹyẹ fun Dokita Ṣapara nitori oye I.S.O. ti Ijọba fun u fun otitọ inu ati iṣẹ rere rẹ. Dokita Ṣapara fesi, o si sọ rafanda oyinbo ninu Agbada-ẹtù nla ti o wọ.

Nigbati ajọ tuka awọn ẹgbẹ Tunluṣe (*Nigerian National Democratic Party*) da muso fun Gomina Clifford ati Sir Donald Cameron nigba mẹta, gẹgẹ bi ilana Ọgbẹni Herbert Macaulay (Ejongboro) ẹniti o ṣe bẹbẹ nijọ na. Lẹhin eyi, a ṣe ipade ẹgbẹ Tunluṣe ni *Glover Hall*; awọn alejo ti a yan si Igbimọ Aṣelu ni Calabar ati Oniṣa si wa nibẹ pẹlu. Lọya Ata Amonu, ọmọ Ọba Amanabu ti ilu Aganyin si fesi ologbon si ọrọ lakaye ti Oloye Oluwa sọ. Ajọ tuka ni dede ago mẹfa abọ pẹlu ayọ ati ọpẹ fun Ọbagiji, nitotọ Ọba bi Ọlọrun ko si.

Ajagun molu! a si bẹ gbogbo ilu pe ija lo ẹ l'orin d'owe, ija ko yẹ ọmọ enia. Ẹ jẹ ki gbogbo wa jumọ wa ni irẹpọ. Awọn mẹta la dibo fun l'ọjọ idibo, ṣugbọn obi awọn mẹta ko yan. Nijọ na ẹ o ranti pe lekeleke mẹ fo loju ọrun nitosi *Glover Hall*. Lana ẹwẹ, nigba ibura ti Ijọba, lẹhin ti Dokita Jones ati Lọya Moore ti bura tan, bi ikẹta wọn Lọya Shyngle ti nbura lọwọ bẹni agogo tawa (*Tower, Secretariat*) lu agogo mẹta mẹta. apẹrẹ nla ni eyi. Ekini kẹbẹ, Ekeji kẹbẹ, Ẹkẹta ajẹjẹtan. K'Ọlọrun ma ṣe jẹki ire tan ni ilu Eko tiwa yi. Aṣẹ!

Emi ni tirẹ nitotọ,

ATARI AJANAKU.

## GBỌN-GBỌN KAN KO SI, AFI ẸNITI O NTI ARA RẸ.

Eyi dabi ibere ọrọ, nitori ẹniti o ba bere ọrọ li o nfẹ idi rẹ gbọ.

O ya ni l'ẹnu lati tun ri aṣa titun ti o tun ṣẹ de si arin awọn Amadiyya, eyiti a ko ri ri, ti a ki si gbọ ri.

Ni ọjọ ọsẹ ti o lọ yi, 14/10/23, ni a tun ri awọn ẹlẹsin yi ti nwọn tun lọ ṣe Igbeyawo kan ninu ile ti a kọ fun Ariyá ati Ijó oriṣiriṣi (*Empire Hall*). Igbẹ adiẹ ko dara ninu Moṣalaṣi, ṣugbọn itan rẹ dara li ori irẹsi; bi o ba jẹ wipe o dara lati ma gbe Iyawo ninu ile ti a kọ fun ọti ati ariya (eyi awọn papa npe ni Bidiva) o dara lati ma ṣe bidiya papa, nitori nwọn ṣe Wãsi de ibi wipe ki a ma de ibiti nwọn gbe nmu ọti; eyi fihan wa gbangba nipa ọrọ ti "AJILARAN" ti nsọ fun wa nipa pipọn ti o ti npọn Esin yi, wipe, A-ti-ọsan ti àbaja ni on papa, ati wipe ko ri nkan ti on nsọ Kẹrẹkẹrẹ, inu Ẹlẹdẹ a wọ ọgba o; bi o ba ya awọn Amadiyya a ma lọ soyigi ninu Iga Ọba, tabi Iga Oloye, tabi ni gbangba Ita Balogun.

A-TI-O-TI.

[Ewo ni AJILARAN sọ si ẹ̀fẹ̀ yi o?
*Editor*,—"Eko Akete."]

## EKO AKETE.

Eko, Saturday, November 3, 1923.

OJO TO PA ILE ỌBA, ẸWA LO BU SI. IGBIMỌ AṢOFIN ILU D'ODE.

TANI PE NKAN ṢE NKAN? TANI PE KINI ṢE KINI?

Arúgúdù ojo to ṣú si ẹgbẹ ọrun niwọn igogo mọkanla ãrọ ku bi ogun iṣẹju ni ọjọ Alaruba (*Wednesday*) ọsẹ yi—ọjọ to bori ọjọ fun Igbimọ Aṣofin Ilu ti Gomina fi aṣẹ si—dẹruba ni diẹ pe boya ojo nã le gba ọjọ kòrú, ko si da nkan ribiribi ọjọ na rú, ṣugbọn nigbati o di bi iwọn agogo meji ọsan kọja diẹ to si dá, la to wa mọ gbangba pe ojo ọjọ na, pẹtù si õru ti iba mu ẹgbã-aimọye enia ti nwọn lọ sibi ẹyẹ na.

ṢIṢI IGBIMỌ AṢOFIN.

Nigbati o di iwọn agogo mẹta ku ogun iṣẹju, lẹhin igbati a ti de Gbangan Ile Iṣofin na (*Council Chamber*) ni awọn Ẹgbẹ olódòdó ti fere bọ 'nu lati wi fun gbogbo enia to wa nibẹ pe Gomina Agba Hugh Clifford oloye nla G.C.M.G. de; were ẹlẹgbã ti wo awọn ọmọ-ogun ti nwọn ti pa amọ dẽ, ni awofin; ṣaju eyi fere nwọn nsan ãra, nigbati nwọn na ẹnu gan orin "Ki Ọlọrun da Ọba si," bi iṣẹju Gomina ti goke ni 2.45 p.m. gbogbo awọn ọlọla ti awọn wa ni Gbangan na ati awọn oworan miran ti nwọn wa loke pẹtẹsi na pelu dide duro bi "I"; gẹrẹ bi jagun ti duro lo bura, lẹhin eyi ni gbogbo awọn ọlọla na bura ni ọkọkan ti oyinbo ti enia dudu.

Akoko ti awọn ara wa to jẹ enia dudu bura leyi:—

| | | | |
|---|---|---|---|
| Kitoyi Ajasa ọlọla | ni | 2.43 | ọsan (p.m.) |
| S. H. Pearse ọlọla | „ | 2.48 | „ „ |
| Adeniyi Jones ọlọla | „ | 2.49 | „ „ |
| Ata Amọnu ọlọla (ọmọ-ọba) | „ | 2.50 | „ „ |
| Obianwun ọlọla | „ | 2.54 | „ „ |
| Isaac Mba ọlọla (Ijoye) | „ | 2.55 | „ „ |
| Eric. O. Moore ọlọla | „ | 3. | „ „ |
| J. E. Shyngle ọlọla | „ | 3.1 | „ „ |

WAYA AJỌYỌ TI GOMINA RIGBA. LATI ILU ỌBA.

Lẹhin ibura yi, ni Gomina ka Waya ti Ọga awọn Gomina ti a npe ni Oloye *Devonshire* fi ṣọwọ si i lati ba a yọ ati gbogbo Ilu fun dida Ajọ Igbimọ yi silẹ; lọjọ na Gomina si tun ka ẹdà waya ti on papa fi ṣọwọ si Ọba *King* loruko ilu *Nigeria* lati dupẹ lọwọ Ọba *King* fun iyọda dida Ajọ Igbimọ na silẹ; eyiti o kọ jẹ akọṣe ni gbogbo ilẹ Ọba *King* to wa ni iha ihin Iwọ Orun Afrika.

IGEDE IWE TI GOMINA FỌ.

Gẹrẹ bi a ti fori eyi ti, ni Gomina ka iwe rẹ (*Address*) to ti kọ fun ọjọ na ninu eyiti o sọrọ pupọ fun ilọsiwaju Ilẹ *Nigeria*; ati lati ma n ãyè fun irufẹ ọkunrin kan to ti wa ni iṣẹ Ọba nibi (P.W.D.) ri, ẹniti o jẹ ara Ibo; ṣugbọn nigbati o de ilu rẹ to si lọwọ ninu fifi ọmọ enia ẹda ẹgbẹ rẹ rubọ, Gomina si sọ sinu iwe rẹ na pe ki a maṣe tun gbọ ohun to ṣẹlẹ nibi lẹnu oṣu mejì to kọja laye mọ; ohun ti ko ṣe enia tabi ilu ni rere kan. O sọ ti iwe owo nina ọdọdun (*Annual Estimate*) ti a o muwa siwaju awọn ọlọla Ajọ Igbimọ na ni oṣu *January* to mbọ.

ẸNYIN ONIṢOWO EKURỌ ATI EPO. Ẹ BU SAYỌ.

Ayọ ọpọlọpọ lo jẹ fun gbogbo awa ti a wa ni ipaṣe yi lọjọ yi nigbati Gomina sọ ninu iwe rẹ ti o ka pe on yio din owo ibode ti Ijọba ngba lori Epo, Ekurọ, ati Ẹpa ku. O ni owo Ibode na yio wa bi o ti wa ri ṣaju ọdun 1920; kosi ẹniti ko ṣapẹ fun ọrọ yi, nigbati Gomina sọ ọ, nitoripe eyi yio ji owo ti o ti nsun yi pẹpẹ, awọn ara wa t' oyinbo t' enia dudu yio si le "ta putu" diẹ ninu owo na.

Gomina ni owo ibode lori *Cocoa* ti a nmu lọ si ilu miran laiṣe ilu oyinbo yio ṣi wa bi o ti wa na fun sa diẹ, ki Ijọba to le da didin rẹ ro bakanna. O si sọ pe awọn Ẹgbẹ

Munisipa yio ma bojuto owo ti nwọn ba ngba lọwọ Ilu fun ara wọn lati oni lọ. Kika iwe ijihin yi gba Gomina ni nkan bi iṣẹju marun di-ladọta tabi ju bẹ lọ.

### ỌWỌ NI ARA NJẸ.

Gomina ni a ko ni ma larukọ mọ awọn ọlọla na lori, bi ẹnikan ba nsọrọ ninu Igbimọ na; ẹnyin Ilu ọrọ pataki leyi: ẹ jẹ ki a tun nyin ni apẹrẹ kan eyiti a gbọ lọjọ na ninu Ajọ Igbimọ. Nigbati ọrọ kan Ọgbẹni J Egerton Shyngle ọlọla, orukọ oye rẹ ti a fi pe e leyi:—*The first Lagos Member* eyini ni Aṣoju Eko Kini; nje lọna eyi, Ọgbẹni Eric O. Moore ọlọla jẹ *Second Lagos Member* tabi Aṣoju Eko Keji; Ọgbẹni Oniṣegun C. C. Adeniyi Jones si jẹ *The Third Lagos Member* eyini ni Aṣoju Eko Kẹta; ara, ẹ fi eyi sọkan o, Ipo ọla to ju yi lọ di ṣàṣà; ẹgbafa to pe ni Igba Ifa; a ko ba awọn to njijadu lati de ibi yi nijelo wi, ibaṣe iwọ nkọ?

### CAMERON OLOYE ATẸRẸ KAN RI, ẸKUN-BABA-ODẸ

Cameron Oloye ka ohun ti Igbimọ ma ṣe lọjọ na, o si dahun pupọ ibere ti awọn Ọlọla na bere lọwọ Ijọba.

Oyinbo Ọgbẹni V. R. Osborne Ọlọla Aṣoju awọn Ẹgbẹ oniṣowo Eko bere Ibere mẹsan.

J. Egerton Shyngle Ọlọla bere Ibere mẹfa, Oniṣegun Adeniyi Jones Ọlọla bere Ibere mẹrin, Eric O. Moore Ọlọla bere Ibere meji, S. H. Pearse Ọlọla Aṣoju Abẹokuta bere Ibere mẹrin.

Gbasan-nṣubu ni awọn Ibere wọnyi ati Idahun wọn; nwọn gùn pupọ, aye ko si sí fun wa nibi lati tẹ wọn; ṣugbọn lori pe ki nkan bi òwò ẹ̀kọ́, Ilera Ilu, ati ohun bawọnni le dara ni nwọn ja si.

Olofin-Ijọba (*Attorney General*) ka ọgọrọ ofin ti awọn Igbimọ Ọlọla na ma fọwọsi; ọkan to ta wa kiji ni ti ofin kan ti a o fi jẹ ẹniti o ba sọrọ ọkukoku laidara ni ya; ṣugbọn Agbẹ jọro-Ọba na si wa la a pe ki-iṣe ki taja t'ẹran mã lọ rá ẹnikẹni mu pe o sọrọ oku ẹbi tabi ara on kan laidara; o ni on ni lati wa bi o tọ bi ko tọ ki on to fi awọ mimu ẹnibẹ ti a ba fi sun; ẹnu awọn ofin wọnyi ni awọn Ọlọla Igbimọ nã si nisinsinyi.

### YIN-NI-YIN-NI- KA ṢE OMIRAN

Lẹhin gbogbo eyi ni Ọgbẹni Kitoyi Ajasa Ọlọla dide damọran pe ki Ilu *Nigeria* dupẹ atọkanwa lọwọ Gomina fun irufẹ anfani to fun wa yi, iru eyi Eko koiti gbọnju ni ri lati igbati o wa labẹ abo Ọba *King*. Ọgbẹni Archer Oyinbo ati Ọgbẹni V. R. Osborne awọn Ọlọla si gbe imọran na lẹsẹ; Ọgbẹni J. Egerton Shyngle Ọlọla si kirin Ọgbẹni Ajasa Ọlọla lẹhin fun ọrọ yi; Gomina si ṣe "hiọ. hiọ" (*hear hear*) si ọrọ Ọgbẹni Shyngle na, awọn Ọlọla toku si patẹwọ si i.

### ABURO KIRISI GBA IYI O GB' ẸYẸ

Lẹhin gbogbo nkan wọnyi ni Gomina fi oye I.S.O. ti Ọba *King* ti fi ranṣẹ si *Dr.* Oguntọla Ṣapara fun Ọgbẹni na, o si "pin" rẹ mọ laiya gbàgbà o si bọ ọ lọwọ pẹlu ọrọ iwuri; ariwo sọ lẹ atẹwọ si dun 'lẹ; *Dr.* Ṣapara si f' ẹsẹ to tọ si ọyẹ nã.

Gbogbo awọn Ọlọla to wa ninu Ipade Igbimọ ọjọ na jẹ mejilelọgbọn ti funfun ti dudu; nigbati Gomina si nbọ nilẹ, lẹhin ipari Ipade ni Agogo mẹrin abọ aṣalẹ beni Ọgbẹni Herbert Macaulay dá Muso fun u ati aya rẹ awọn Ẹgbẹ Tunluṣe ti nwọn ti pé bibà si Agbàlá Ile Iṣẹ Ilu nã (*Nigerian Secretariat*) pẹlu asia wọn ti awọn omidan to ti kato gbe, si hó kũ; bẹ tun ni Ọgbẹni Herbert Macaulay tun dá Muso fun Oloye Donald Cameron awọn Ẹgbẹ si ho Iho ayọ; ati Gomina ati Cameron Oloye nla si rẹrin muṣẹ; nwọn si kan sara si awọn Ẹgbẹ *Democratic* na pe gbere rẹ ẹ ẹ ẹ.

Bẹni a si ṣe fun awọn Aṣoju Eko mẹtẹta nã ati *Dr.* Ṣapara; lẹhin eyi ni awọn Ẹgbẹ na pada lọ f' ogo fun

)lodumare fun yiyẹ to yẹ ẹgbẹ yi lọjọ ıã.

A tunṣe Ipade Igbimọ yi ni Alamisi (*Thursday*) ọsẹ yi, lẹhinna ajọ ko tu o, ıti di osu *January* to mbọ gẹgẹ bi a ti ṣọ nişaju.

Tani lawa o ni Baba,
Ṣai A ni baba !
Gomina Clifford baba wa,
Ṣai A ni baba ! !
Cameron Oloye baba wa,
Ṣai A ni baba ! ! !
Muso ! Muso ! ! Muso ! ! !
K' Ọba ko pẹ ! ! !.

---

**WHAT A PASS !!!**

Yes ! what a pass things have come to.

Happenings precedented and unprecedented have made their terrific or mild appearances as the case may be, but I must confine myself to an unprecedented happening, terrific in its tragedy, and so far as the person who met this tragedy, frightful to reason, and which shows the terrific power of human diabolical vengeance, one of the wearers of the white hair symbolical of supreme Justice despatched within the very precincts of courts of Justice. Imagine the terror of the populance of August 25th 1923, Saturday.

As they fled in
terrific routs
Each man stunned, staggered
and routed
By the cruel example of Fate.

This incident is probably unprecedented all the world over, and it is even certain that nothing like it has ever happened in a Court of Justice. Opinions differ as to the aftermath of this incident. Murder and suicide have been treated by Juries (under special circumstances) as proceeding from one of unsound mind i. e. without malice aforethought, for the madman may be under the impression that he is breaking a jar or so. But, murder without malice aforethought is manslaughter which is not usually accompanied by sentence of death. Murder with malice aforethought is when a man has in his mind to kill his offender as soon as opportunity offers, in order to revenge himself on the man, he thinks has wronged him so that we see that murder has "revenge" for its origin but manslaughter "dispute" for its origin. A suicide or murderer was at one time disallowed to be buried on consecrated ground, but would seem that the natural conscience of man revolted later against the idea hence before 1882 the English Jury were fond of adding to their verdict a rider "suicide (or murder as the case may be) while of unsound mind." This brought about the passing by Parliament of the "Interments Act 1882 that rescinded the custom of burying the suicide (or murderer or both) on unconsecrated ground." In the midst of life we are in death, and who knows what next? The atmosphere after this tragic incident was very foreboding An evil inspiration travelled like wild fire through the hitherto sacred regions of the hearts of Lagosians. But this cruel inspiration was macifully smothered by the Providence through His word, and through the sane opinions expressed by the Press.

May the good Lord save us in Lagos, and bless every effort for the true interpretation of the Law among us.

What a pity.

CLYPEUS.

---

## From "Nigerian Who's Who."

**VAUGHAN, WILSON JAMES.**

Merchant (Ironmongery) born 1866, educated at Christ Church Faji, and at the C.M.S. Grammar School 1880; lost his father 1893; is a Deacon of his Church (Ebenezer Native Baptist;) is a gifted poet; published *The Dynamite* in honour of his 49th birthday, 1915, chief of his poems include *Agogo Eleko* published in our language, 1908, *The Young Widow*, The *Christian Warfare*; has donated many a charitable movement. died at sea on his return from England with his brother Mr. B. C. Vaughan to Lagos, and was buried in Gambia October 1923.

---

## IROHIN LATI PORT HARCOURT.

Ni ijọ kẹtalelogun oşu yi ni awọn igbimọ Ijọ Wesley da alakoso ijọ yi duro nitori ipalara owo ijọ yi ti wọn ri. A ni ireti pe owo ti awọn ẹlomiran fi agbara kaka da si ile Ọlọrun ni a sin gbọ wipe owo na di ti ẹlomiran lati fi gbọ bukata ara rẹ. "Eyi ma şe kilibọ o" A gbọ wipe alakoso na fi ọwọ siwe wipe on yio san owo na. Iwa aişotọ (*dishonesty*) wa dara ni ile Ọlọrun? Ki awọn agba ijọ ni Eko ki wọn ba wa fi oju si ọran na ati pe ijọ yi bẹbẹ fun Ojişẹ Ọlọrun ati olufọkansin otitọ. Awọn igbimọ nreti ọga Oniwasu lati Eko lati wa pari ọrọ na.

### ẸJỌ ALARINRIN.

Awọn ara ilu Bonny pe awọn ara ilu Owerri ni ẹjọ fun ibajẹ ohun elo ti wọn fi şere ni ọdun *1922 December*. Ẹjọ na wa ni Ganran nisisiyi ni Port Harcourt—ẹjọ yi jẹ gbagidari—inu wa yio dun lati gbọ bi ẹjọ yi yio ti pari si—Ẹjọ yi ni ogbe *Lawyer* Thompson dide ni Eko-Ọgbẹni yi nsọ boto ọrọ. Awọn ti wọn wa si kotu fun ẹjọ yi ni ojojumọ le ni ẹgba 200 enia ti ile ati ode kun wọbi.

Awọn *Lawyers* ti Bonny gba ni wọnyi:—Gibson, Clinton ati Amonu.

Awọn *Lawyers* ti Owerri gba ni wọnyi:—Graham Paul ati Thompson.

A rika ni inu Eko Akete ti ọjọ *October* 20 pe lati Port Harcourt de Ẹnugun jẹ *157 miles* eyi ko jẹ bẹ arara, yio si jẹ ohun işina fun awọn ẹlomiran ti wọn ko ti mọ ilu wọnyi. Lati Port Harcourt de Ẹnugun jẹ *151 miles*. A si tun ka ni inu iwe yi pe Ovim Station ni on ẹniti o kọ iwe na—ki ni oluwa rẹ le wi ti

o ba ri Aba Station, Umuahia Station tabi Ẹnugun papa, ka nbọsibọsı Baba Station ti ọwọ ilẹ ibi Port Harcourt. Ko si ohun ti o wa ni Ovim Station ju okuta pupa lọ—eleyi fẹ jẹ a lọju ma mọran wo.

## THE NIGERIAN LEGISLATIVE COUNCIL ELECTION.

We are bound to take a lively interest in the new regime inaugurated by the election of three members to form the new Legislative Council of Nigeria brought about by the initiative of the National Congress of British West Africa. Whatever may be said to the contrary, it is a matter of history, that this concession is a partial reply of government to what may be regarded as the main plank of the Congress Programme of privileges sought for from government by the London Delegation of the Congress in 1920.

Our sister Colony of Nigeria took the lead and was the first to announce the change of policy. It is therefore a matter of anxious interest to watch at a distance how she has fared and what she has made of her privilege. It is greatly to be deplored that there has been for a long while, a state of better dissention, sometimes tending to personal animosities, amongst those who should be leaders of the people. In our judgment this has been mainly due to a lack of that public spirit which should recognize every one in the community, however humble in station, as an integral part of the whole and treated with becoming decorum and due consideration. There seems to exist a sort of despotic conservatism which has entirely stood in the way of the rich helping the poor and the poor loving the rich as in the old days of Rome. The pity has been, that such an unwholesome attitude has been allowed to grow in intensity to the extent that it has lent itself to acts of lawlessness and bitter revenge, a condition of affairs which has quite removed the political contest of that community away from the platform of a healthy legitimate election campaign, as obtains in civilised countries.

We are sincerely sorry for this and would appeal to every true lover of country in that community to see the reasonableness of burying the hatchet and rising above petty differences and such bitter animosities as may be gleaned exist from the severe and, we trust, exaggerated description of present condition by a section of the press, of the moral and intellectual stamina of the people in general of that otherwise most fortunate colony.

It is undeniable that the mebers of the National Democratic Party have won the confidence of the people. We are sorry that there should be any cause for any one to suggest that such an achievement has been secured through base and unworthy agencies. In our mind, it would not be enough to justify such allegations by just sweeping statements; but there is a moral responsibility on those who make them, to bring cogent facts in substantiation of their indictment, if they must be listened to by sensible persons. Whatever allowance, we grant should be made on the ground that the movement is new and a certain measure of incongruities must be allowed, we contend it should not take the form of indicting practically the whole community with acts of miscreancy and villainy. We have read with severe pain the withering strictures of our contemporary the *Nigerian Spectator*, and have been wondering what wave of diabolism has resently surfeited the people, if those pronouncements are something more than the imaginary.

We are forced to ask, have the Christian Churches [...] their influence? Can it be true that such a swift [...] wholesale degeneracy could so soon have afflicted [...] people for whom we had along treasured high re[...] and affectionate, confidence? We cannot imagine [...] even a moment, that any one could be so infatuated [...] whatever the cause may be, as to forget what ter[...] and baneful consequences may follow such allegat[...] as have been made against a large section of [...] community.

Is it possible that a distinguished personage as [...] Oluwa a princely great-heart, whom we have lear[...] venerate and love could lend his lead to followers [...] have been described as lawless, diabolical, and [...] worthy? We have noticed that the three [...] candidates from the National Democratic Party [...] nominated by the White Cap Chiefs.

Are not these men true and loyal to government? [...] they not respected by all?

[ *To be continued* ]


## MOTOR LAUNCH ẸPẸ.

Sapẹlẹ, Ejinrin, Ẹpẹ, Koko, Gbẹkẹbọ, Ikor[...] Badagry, Portonovo, Kutọnu, Ọjọ ati ibikibi [...] wa li Eko ti ko nṣe ọna okun.

Ọkọ wa yio ma lọ ni ọjọ Ọja, ẹniti o ba [...] lati haya rẹ le wa ri Akọwe Ọlọkọ na ni Ebu[...] Ero, a o sọ iye owo hihaya rẹ fun.

A ko kọ ẹnikẹni lati haya rẹ fun Ọni, A[...] Atijirẹ, Arogbo, Abori, Ṣiloko, Ofonoama.

Ni ile GAISER lailai ni Ebute-Ero.


## *IN MEMORIAM.*

"Gone! but never forgotten
Green! will his memory be
Though his death be like a dream."

In loving memory and affectionate remem[...] brance of my dear Friend and Pastor,

REVD. S. M. ABIỌDUN, M.A.,
*Superintendent of Ẹgbado and Awori District*

Who, on Thursday the 31st day of Ma[...] 1923, six months ago, resigned [...] tenement of clay, for the glories of [...] upper Sanctuary, where all ranks [...] levelled and all distinctions are done awa[...]

Friend and Pastor, thou art gone up on high
Resting in the bosom of Christ;
Where all earthly cares of grief,
Cease to trouble thy peace of mind,

*Rest in peace.*

20 Igbosere Road,
Lagos, 31/10/23.

ISAAC B. THO[...]

## IGBẸ L' OWO WÀ.

**LAGOS—EKURO.**

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja Produce) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.
£12 10—£12 15 fun *ton* kan.

EPO.

£24 10—£26 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£18 10—£19 fun *ton* kan bakanna.

---

**KANO**—COMPETITIVE PRICES
Ground Nut—
Skins 1/9 per lb, Hides 5d per lb

---

OKARE, ỌMỌ ORIMAYAKI AGBOJO LỌWỌ IKU, ABẸRU ỌBA MA BẸRU ẸNIKAN.

O jẹ didun inu wa lọpọlọpọ lati gbọ pe Awọn ẹbi Ijoye Taiwo Olowo fi Ọgbẹni Ephraim Conrad Taiwo agba ọmọ ologbe Ijoye na jẹ Oleri Ile Taiwo Olowo ni ọjọ 29 Oṣu tokọja ati pe Kõtu si fi ọwọ si Ipo na.

Oku ọmọ Agbo-dere ni'le Iṣẹri.

---


## AIYELẸSỌ ỌLARINDE

Repairer of all kinds of Bicycles, Gramaphones Fitting and Sewing Machines.

*Workshop* :—20, Williams Street **Lagos.**

*Residence* :—135 Igbosere **Road.**

**Charges Moderate.**

**Cable Address :—**
"Steinafrik" HAMBURG.

## E. H. STEIN & Co.

**HAMBURG, Neurwall 16/18, Hildebrandhaus.**
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No.* 505.

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
Broad Street, & Portonovo Market Store.

---

ẸGBẸ OYINBO ONISOWO
E. H. STEIN ARA HAMBURG.
NEUERWALL 16, 18, GERMANY.

Jẹ awọn onişowo ti ilẹ Enia Dudu, nwọn ma nranşẹ Ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ, ibaşe Ọja ti ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu Oyinbo miran ti o wa lagbegbe *England* ati *Germany*.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranşẹ si wọn si ilu awọn Oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi Ọja-kọja ranşẹ si wọn lati Eko tabi ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn Oyinbo yi şowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-işẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-iti Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) l'Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Orukọ adugbo awọn Oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK, Hamburg.


---

"EKO AKETE" GB'ỌRẸGẸJIGẸ.

A le ri Iwe-irohin yi ra lọdọ :—

(1) Ọgbẹni VIDAL R. COLE, Ajenifuja Store 109 & 111, Broad Street, Eko.

(2) Ọgbẹni S. A. YEWANDE, 146, Griffith Ebute Meta Street,

(3) Ọgbẹni MOSES O. JONES GOI, Itẹsi, Abẹokuta.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 3 p.m. | (HARVEST) | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. J. A. Angus |
| 7 p.m. | do. | „ A. N. Cole |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | do |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 3 p.m. | (HARVEST) | „ S. J. Gansallo |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev S. A. Pearce |
| 7 p.m. | do | do |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. A. Laleyẹ |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. A. Laleyẹ |
| 7 p.m. | do. | do |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akinọla |
| 6.30 p.m. | | Bro. H. T. King |
| 9 a.m. | Zion | Rev. N. J. D. Shomuji |
| 3 p.m. do. | (HARVEST) | „ J. F. Ogunko |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Rev. I. O. Oyekunle |
| 4 30 p.m. | | Bro. E. A. Williams |

FIRST BAPTIST CHURCH

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. O. J. John |
| 6 30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Rev. A. A. Puddicombe |
| 5 p.m. | | do |

EBENEZER (BAPTIST)

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. E. A. Ojo |
| 6.30 p.m. | Rev. E. C. Alabi |

BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Prof: Adeoye Deniga |
| 7 p.m. | | Pastor A. Adedeji Isọla |

St STEPHEN'S (EPETEDO)

| | |
|---|---|
| 9 a.m. & 4 p.m. | Rev. A. Adekọya |

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde

5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajose (Bamgboṣe Street.)

COLONIAL CHURCH (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

SALVATION ARMY.

| | |
|---|---|
| 10 a.m. | Lieut-Colonel Geo: H. Souter |
| 7 p.m. | do |

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread

7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, T. W. Walleace & Wm. C. T. Terry

---

### Change of Address.

Mr. S. T. Ọderinde Ladega begs to inform his friends that he is removing from No. 48 Agodokomeh Street, to No. 5 Okoya Street, (*Idoluwo*) with effect from the 1st of November 1923, and that all communications intended for him from that date should be directed to the latter address.

---

### Change of Name.

Mr. ABDUL-GAPHARR S. FAHM begs to notify the public that on and from the 1st. day November 1923, he desires to be known and addressed as ABDUL-GAPHARR S. EDIDI.

All papers or documents signed by him prior to that date and bearing the former name remain valid.

*The Ile-Sanmi Chambers,*
*89 Palm Church Street,*
*Lagos, Nigeria.*
*October 22nd. 1923.*

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION.*

TO

**S. I. M. Johnson,**
9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

***Wool, Wool, Wool.***
***Silk, Silk, Silk.***

Wulu tabi Siliki lo nfẹ ra ọmọ iya mi? Lọ si Ṣabu Iya Labu, nibẹ ni iwọ yio ri ni oriṣipe, Wulu ati Siliki lo fi ṣiṣẹ ṣe—Kọbọ ẹru.

(Abulati mbẹ pẹlu bi tẹdi, ọmọ iya Siliki ni.)

18 & 137, Victoria Street.

ẸNIKEJI,

Aṣọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

FOR SALE

One upright grand Iron-frame Piano, with beautiful tone. New condition—Owner going on leave, and will repurchase on his return six months.

For Terms, etc., apply to the EDITOR.

JUST THINK OF THAT.



Persons desirous of selling or acquiring Houses or Land in the Colony of Lagos should communicate with

E. SOYEMI ALDER

who for many years has specialised in this class of Property. Sales effected by Public Auction or Private Treaty. Valuation for Mortgage or Probate carefully prepared. Loans arranged Commissions reasonable.

☞ Please note address:—E. SOYEMI ALDER, Auctioneer, Valuer, etc., Owode (opposite the Law Courts) Tinubu Square, Lagos.

**The Union Night School.**

FOUNDED JAN. 1923.

The School prepares candidates for Cambridge, Preceptors and Government Clerical Examinations and also teaches all Infant and Primary subjects, Yoruba inclusive.

The School opens on Mondays, Wednesdays, and Fridays in the Breadfruit School (Top floor) For further particulars apply to

*THE SECRETARY,*
Union Night School,
P.O. Box 121,
Lagos.

ILE IWE ALẸ.

A da Ile-iwe alẹ silẹ fun gbogbo ọmọ Ile-iwe ati oṣiṣẹ pẹlupẹlu fun awọn ti o nfẹ lati ṣe idanwo fun iṣẹ Ọba ati *Cambridge*, a si nkọ iwe Yoruba nibẹ. A nṣe Ile-iwe yi ni ọjọ *Monday*, *Wednesday* ati *Friday* ni agogo meje abọ alẹ ni Ile-iwe *Breadfruit* (Loke.)

## AWORAN ALARABARA.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣe ile l'ọṣọ. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a lẹbi iku, ti onjẹ alẹ ikẹhin, t'owo lowo, a ni ti Adam ati Efa, ti iṣẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ọla ati ijọba rẹ ati nigbati o di ẹranko,' ti obinrin ti o fi ọwọ mu ejo, ti Ọba Tatambulu.

Awọn Aworan wọnyi mbẹ bi aba, nwọn si pọ tase. Bi o ba fẹ ko pupọ, a le din ọ ni owo diẹ ki o ba le ri tirẹ jẹ. Iye owo wọn 3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan. 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila tabi *dozen*.

A ni Ewe-taba fun kika ta, Ọṣẹ-olowọ agaga, Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ bi wọbu, bi o ba fẹ tọn a le ta a fun o, Iṣana alapoti fun tita ko si bi a ti nṣe wọn, oriṣiriṣi ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa ṣowo ko ma ri tirẹ jẹ, nitori owo pọku ni a nta wọn, owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile Ọja wa, kami-kami ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ ja iọ wa, rin wa sibẹ.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin okun kowe ṣowọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si :—

E. O. AMBẸ & BROS.,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
(*Lẹgbẹ awọn Oniṣowo A. J. Tangalakis*)
Idumagbo.

---

## FOR SALE.

One Second Handed Triumph Motor Cycle in good working order.

Kick Start, 3½ H.P. with best magneto (Bosch) complete with front and rear lamps. Available for inspection.

PRICE : MODERATE

Apply to the Editor

---

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless va[riety]
at 50, Dosunmu Street, Lagos,

**Prices to suit everybody,**

*Call now, fortune awaits you.*

---

## OGUN YANMUYANMU AT[I] EṢINṢIN.

(*Fly Catcher.*)

Eṣe ti o fi njẹ ki Yanmuyanmu [ati] Eṣinṣin ko arun ba ọ, nigbati ogun [wa] ni arọwọto rẹ. Ẹgbẹrun pere ni... Ẹdẹgbarun fun mejila (2/3d a dozen)

A si ni ipari olorun amu irun daradara, o si ma njẹ ki irun ... njẹ ki o ma kọmọna bi jigin, ari mal[e] pada ẹhin. (*Hair preparations.*)

Kọwe tabi bere l'ọdọ
DIPO TUNDE & Co.
P.O. Box 335.
30, Victoria R[oad]
Lagos, Nig[eria]

---

## A CHANCE FOR THE FIT

IN THESE *HARD TIMES* !!!

Wanted, a good Salesman capable [of] managing

**A Goods Shop**

*Salary Liberal*

Only those with substantial Security [need] apply to the EDITOR of this paper.

---

*Ibi ni ẹnyin ro si ni:—Ṣugbọn Oluwa ...*

OKANLAWON BALOGUN BROTHERS

Dealers in best quality of Produce viz:—C... Kernels, Palm Oil, Skins of any kind etc., etc.

*Head Office* :—16, BANKOLE STREET, Lagos

*Branches at* :—Lagos, Agege, Agbado, Ilo, ... Wasinmi, Owowo, Ibara, Lal... Ibadan, Ileigbo, Iwo, Ikirun ... Oshogbo.

*A trial order will be thankfully solicited.*

---

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.